# IFARARUBỌ HANNA

## (ẸKỌ FUN ỌJỌ AWỌN IYA)

## 1 Samuẹli 1:1-28

## ẸKỌ 71 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Bọ̀wọ fun baba ati iya rẹ (eyi ti iṣe ofin ikini pẹlu ileri), Ki o le dara fun ọ, ati ki iwọ ki o le wà pẹ li aiye" (Efesu 6:2, 3).**

**I Iya Olotitọ Kan ni Israẹli**

1. Aya Ẹlkana ni i ṣe, 1 Samuẹli 1:1
2. Kò bi ọmọ kankan, 1 Samuẹli 1:2
3. Ẹlkana ati ara ile rẹ̀ n sin Ọlọrun gẹgẹ bi àṣẹ Rẹ̀, 1 Samuẹli 1:3, 4; Deuteronomi 12:5-7
4. Hanna ri inunibini pupọ, 1 Samuẹli 1:5-8; 2 Timoteu 3:12; 1 Peteru 2:23; Jakọbu 5:10, 11

**II Ẹ̀jẹ́ Kan fun Oluwa**

1. Ọkan rẹ dàru, o si gbadura si Ọlọrun, 1 Samuẹli 1:9, 10; Orin Dafidi 61:1-4; 66:18
2. O wá Ọlọrun tọkantọkan fun ẹdun ọkan rẹ, 1 Samuẹli 1:11-16; Gẹnẹsisi 32:24-26; 2 Kronika 15:15; Orin Dafidi 38:9
3. Hanna ni ẹri pe a gbọ́ adura oun, 1 Samuẹli 1:17, 18; Heberu 11:4; Romu 8:16
4. Oluwa ranti rẹ̀, 1 Samuẹli 1:19, 20; Isaiah 59:1; 1 Peteru 3:12; Johannu 9:31; Gẹnẹsisi 32:28

**III Sisan Ẹ̀jẹ́ Naa**

1. Ọkan rẹ̀ duro ṣinṣin ninu ipinnu rẹ̀, 1 Samuẹli 1:21-23; Gẹnẹsisi 22:1-8; Heberu 10:7
2. O mu ẹ̀jẹ́ rẹ naa ti o ti fi ifararubọ ṣe wá, 1 Samuẹli 1:24, 25; Lefitiku 27:28; Deuteronomi 23:21; Oniwasu 5:4
3. Ẹri Hanna fara hàn, o si jẹwọ otitọ Ọlọrun rẹ̀, 1 Samuẹli 1:26, 27; 1 Tẹssalonika 5:24; Ifihan 19:11
4. O jọwọ Samuẹli si abẹ itọju Oluwa, 1 Samuẹli 1:28; Owe 22:6; Jeremiah 17:7, 8; 1 Johannu 3:21; Marku 5:22-43; Matteu 15:22-28

## ALAYE

**Igbe Hanna lati Inu Ọkàn Rẹ̀ Wá**

"On nsọ̀rọ li ọkàn rẹ̀; kiki etè rẹ̀ li o n mì, ṣugbọn a kò gbọ́ ohùn rẹ̀." Hanna ti gbé igbesi-aye ẹni iwa-bi-Ọlọrun: o ti lọ jọsin ni ile Ọlọrun, o ti ṣe ifararubọ ti ode ara, o si ti ṣe ohun gbogbo ti Ofin beere. Ṣugbọn ni ọjọ yii o tubọ fi ara rẹ̀ rubọ si i ju bi o ti ṣe tẹlẹ ri, eyi si mu ere pupọ wa fun un.

Ẹgan nla ni airọmọbi jẹ fun awọn obinrin igba nì, inu Hanna si bajẹ gidigidi bi o ti n tọrọ ọmọkunrin lọdọ Ọlọrun. Dajudaju yoo ti gba iru adura bayii tẹlẹ rí; ṣugbọn bi ọjọ ti n gori ọjọ ti a ko si mu ibeere rẹ ṣẹ, adura rẹ bẹrẹ si i gbona si i. O gbona to bẹẹ gẹẹ ti ọrọ nikan ko le sọ ẹbẹ rẹ -- kiki ọkàn rẹ ni o n kigbe si Ọlọrun. Lati odò ọkàn rẹ̀ wá ni o ti n gbadura, Ọlọrun si gbọ́ igbe rẹ̀.

Adura Hanna jinlẹ: o jiya, "on si wà ninu ibinujẹ ọkàn … o si sọkun gidigidi." Hanna tú ọkàn rẹ̀ jade o si jẹjẹ pe bi Ọlọrun ba fun oun ni ọmọkunrin kan, oun yoo fi i fun Oluwa ni gbogbo ọjọ aye rẹ. O fi ẹbọ bá Ọlọrun dá majẹmu. Ọlọrun mọ pe yoo mu ọrọ rẹ̀ ṣẹ, o si fi ibeere rẹ fun un.

**Ifararubọ Lati Ri Esi Adura**

Awa naa ni lati fi ara wa rubọ patapata ki a ba le ri esi adura wa gbà. Nigba ti a ba tọ Ọlọrun wá fun igbala, a o kigbe bi onitubu nì ti o ri bi a ti gba Paulu ati Sila ninu tubu lọna iyanu: "Kini ki emi ki o ṣe ki ng le là?" O n fẹ kọ ohun gbogbo silẹ lati mọ Kristi; bẹẹ ni awa naa ni lati fi ohun gbogbo ti o wà ni ipa wa silẹ nigba ti a ba tọ Ọ wá pẹlu ironupiwada.

Ṣugbọn lẹyin ti a gba ọkàn wa là a ri i pe a ni lati ṣe ifararubọ ti o pọ ju bẹẹ lọ ki a ba le sọ wa di mimọ́ patapata. Paulu wi bayii fun awọn ara Romu: "Nitorina mo fi iyọ́nu Ọlọrun bẹ̀ nyin, ará, ki ẹnyin ki o fi ara nyin fun Ọlọrun li ẹbọ ãye, mimọ́, itẹwọgbà, eyi ni iṣẹ-isin nyin ti o tọ̀na" (Romu 12:1). Ọlọrun n pe wa lati ṣe ifararubọ ti o jinlẹ ti yoo mu ki iwa mimọ́ kun inu aye wa: nigba ti a ba si mu ọkàn wa wá si ipo bayii nipa jijọwọ ohun gbogbo silẹ patapata fun ifẹ Rẹ̀, Oun yoo mu ki ina sọkalẹ sori ẹbọ wa, yoo si sọ wa di mimọ́ patapata.

Eyi ki i ṣe opin ifararubọ. Bi a ti n rin ninu imọlẹ, a n kọ wa lati walẹ̀ jin si i nipa jijọwọ aye wa fun Ọlọrun. Ọkan wa yoo maa poungbẹ fun Olutunu nì lati maa ba wa gbe, Ẹni ti yoo wọ inu ọkàn wa nigba ti a ba fi Ẹmi Mimọ́ ati ina wọ̀ wa. A o fi ohun gbogbo ti a ni fun Ọlọrun gẹgẹ bi a ti le ṣe tó: awọn olufẹ wa, ile wa, gbogbo igba aye wa fun iṣẹ-isin Rẹ̀. Bi ifararubọ wa ti n pọ si i bẹẹ ni igbagbọ́ wa yoo maa pọ si i; nigba ti a ba si de ipo naa ti a

jọwọ ohun gbogbo fun Un patapata, igbagbọ́ yoo rọ̀ mọ ileri naa, ogo yoo si kun inu ọkàn wa. Ọlọrun yoo bu ọla fun Ọrọ Rẹ̀ yoo si ran Ẹmi Mimọ́ lati kun inu ohun-elo naa ti o ṣofo ti a ti yà si mimọ́ patapata, ti a sọ di funfun, ti a ti danwo.

**Imọlẹ ninu Ijọ**

Sibẹ a gbọdọ fi ara wa rubọ si i. Lojoojumọ ni a ni lati maa fi ifẹ wa le Ọlọrun lọwọ ki ina ni ba le maa jo ninu ọkàn wa. Okunkun inu aye n pọ si i, ọmọ Ọlọrun si ni lati jẹ ki atupa oun maa jo geere bi o ba fẹ jẹ imọlẹ fun awọn ti o ti sọnu lati dari wọn si ibi aabo ninu Kristi.

Awọn miiran n wi pe wọn ti ri igbala, isọdimimọ́ ati Ẹmi Mimọ, wọn si ti ṣetan fun Ọrun. Ṣugbọn o dabi ẹni pe wọn kò mọ ohun ti i ṣe ojuṣe ti o ba awọn iriri iyanu wọnyii lọ. "Kò si ẹnikan ninu wa ti o wà lãye fun ara rẹ̀" (Romu 14:7). Ojuṣe Ijọ Ọlọrun ni lati tan imọlẹ ninu aye ti ẹ̀ṣẹ ti sọ di okunkun yii. Awọn ti o ba si n kuna ninu ifararubọ wọn, tabi ti wọn n fa sẹyin kuro lọdọ Oluwa jẹ awọn ti imọlẹ wọn ti di baibai.

Onipsalmu wi pe: "Ọlọrun Olodumare, ani OLUWA li o ti sọ̀rọ, o si pè aiye lati ila-õrun wá titi o fi de iwọ rẹ̀. Lati Sioni wá, pipé ẹwà, Ọlọrun ti tan imọlẹ" (Orin Dafidi 50:1, 2). Sioni ti Ẹmi ni Ijọ Kristi, Ijọ Akọbi, awọn eniyan Rẹ̀ si ni lati kọ tanmọlẹ gẹgẹ bi ẹni kọọkan ki Ijọ ba le gba ogo ki o si tan imọlẹ sinu aye.

Wo iru iwuni-lori nla ti o jẹ lati pade ọkunrin tabi obinrin ti o ya ara rẹ sọtọ patapata fun Oluwa! Ẹmi Ọlọrun maa n tan imọlẹ ninu igbesi aye wọn. Ọlọrun ti fi ọṣọ ti ẹmi kun igbesi aye bawọnyi. "Emi o yọ̀ gidigidi ninu OLUWA, ọkàn mi yio yọ̀ ninu Ọlọrun mi; nitori o ti fi agbáda igbala wọ̀ mi, o ti fi aṣọ ododo bò mi, gẹgẹ bi ọkọ iyawó ti iṣe ara rẹ̀ lọṣọ́, ati bi iyawò ti ifi ohun ọṣọ́ ṣe ara rẹ̀ lọṣọ́" (Isaiah 61:10).

**Sisan Ẹ̀jẹ́**

Ọpọlọpọ eniyan ni wọn maa n ṣe ifararubọ, ṣugbọn wọn maa n fa sẹyin lati mu ileri wọn ṣẹ nigba ti akoko ba to lati ṣe bẹẹ. Ṣugbọn Hanna jẹ́ ẹjẹ fun Oluwa, ko si fa sẹyin lati san an. Ko duro titi di igba ti ọmọ naa yoo dagba ki o to mu un pada wa fun Oluwa, ki o ba le maa gbadun ibagbe ọmọde naa ninu ile; ṣugbọn gẹrẹ ti o ti gba ọmu ni ẹnu rẹ̀ ni o ti mu un tọ Eli, alufaa wá, o si jọwọ ọmọ rẹ̀ ọwọn fun iṣẹ isin mimọ́. O fẹran ọmọ ileri yii, ṣugbọn o fẹran Ọlọrun ju ọmọ naa lọ, o si mọ pe Ọlọrun paapaa fẹran Samuẹli.

Ọlọrun fẹran ọkàn ti o kun fun ifararubọ, o si fẹ iṣẹ-isin ti a fi gbogbo ọkàn ṣe; ṣugbọn ko fẹ ohunkohun ti a ni bi a ko ba jọwọ aye wa fun Un patapata. Ọlọrun ni Oun ni O ni awọn ẹran lori ẹgbẹrun oke, bi ebi ba si n pa Oun, Oun ki yoo sọ fun wa. Ọlọrun n fẹ ki a ya ara wa sọtọ fun Oun de àye ti yoo fi le lo wa lọnakọna, ti a o si gba A laye lati mu eto ti Rẹ̀ ṣẹ ninu igbesi-aye wa. A ba le sọ bi ti Dafidi pe "Inu mi dùn lati ṣe ifẹ rẹ, Ọlọrun mi, nitõtọ, ofin rẹ mbẹ li aiya mi!" (Orin Dafidi 40:8).

**Ifararubọ ti Inu**

Ọlọrun n beere ifararubọ ti inu ti yoo kan ara mọ́ agbelebu; ti ko si ni ka ayé rẹ̀ si eyi ti o ṣọwọn titi de oju iku; ti yoo maa ṣafẹri ifarahàn Rẹ̀ lojoojumọ, ani irẹpọ ailopin pẹlu Ẹlẹda rẹ̀. Paulu wi fun awọn Onigbagbọ́ Kolosse pe: "Nitori ẹnyin ti kú, a si fi iye nyin pamọ́ pẹlu Kristi ninu Ọlọrun" (Kolosse 3:3); o si wi fun awọn ti Kọrinti pe "Nitoripe nigbagbogbo li a nfi awa ti o wà lãyè fun ikú nitori Jesu, ki a le fi iye Jesu hàn ninu ara kikú wa pẹlu" (2 Kọrinti 4:11). Ẹnu ko le ṣe alaye ẹwà ifararubọ ti inu, ṣugbọn awọn ti wọn n lepa lati ni ẹkun rẹrẹ Ọlọrun ni o yé ti wọn si ni in gẹgẹ bi iṣura.

O maa n rọ awọn ti o fi aye wọn rubọ lọrùn lati jiya fun Kristi. Bi o ba jẹ ninu ara ni, ipinya Hanna pẹlu ọmọ rẹ̀ akọbi i ba mu ibanujẹ nla ba a; ṣugbọn o ti jọwọ rẹ̀ patapata fun Oluwa, o si ti jọwọ ifẹ inu rẹ̀ ni ifararubọ patapata fun Oluwa; Ọlọrun si fun un ni igboya lati mu ẹjẹ rẹ̀ ṣẹ.

Nigba ti Jesu ba pe awọn ọmọ Rẹ̀ lati jiya diẹ nitori ti Rẹ̀, wọn maa n sá sẹyin kuro ninu iyiiriwo naa, tabi ki wọn maa kùn si Ọlọrun. O le gba iyiriwo yii laye lati fi hàn bi o ba jẹ pe lati inu ọkàn ni a ti ṣe ifararubọ ni ti a ṣe ni igba iṣoro. Awọn ti o ba gba iyiriwo laye lati ṣe iṣẹ rẹ̀ ni aṣepe ninu aye wọn ni awọn ti n gbadun eso alaafia ti ododo.

**Òórùn Didun lati inu Itanna ti a tẹ̀rẹ́**

Bi iwọ ba n fẹ òórùn didun ti o wa ninu itanna, tẹ̀ itanna naa rẹ́, òórùn didun rẹ̀ yoo si jade. Bakan naa ni o ri pẹlu awọn ọmọ Ọlọrun tootọ. Jẹ ki iyiriwo, ipọnju, ati irora kọlu wọn, lati inu igbesi aye ti a wó palẹ yii ni oorun didun ati ẹwà yoo ti jade wá ti yoo jẹ ibukun fun awọn ẹlomiran. Olukuluku Onigbagbọ́ ti a fi Ẹjẹ nì wẹ̀ ti o la wahala kọja ti o si de ebute Ọrun ni yoo dupẹ lọwọ Ọlọrun titi ayeraye fun itọni nipa ọwọ agbara nla Rẹ̀, ti yoo si wi nigba naa, bi ko tilẹ le wi bẹẹ nisisiyii pe, "Ọna Rẹ̀ ni o dara ju lọ." Ko si ẹni ti yoo kọ itọni Rẹ̀ bi o ba ṣe e ṣe lati mọ ogo ti a o fi hàn ni ọjọ iwaju. Ọpọlọpọ ni o ti tipasẹ idanwo ati iyiriwo, di ẹni ti o wulo gidigidi, alai-mọ-tara-wọn-nikan, ti a si yà sọtọ fun Ọlọrun.

**Èrè Hanna**

Nitori ifararubọ Hanna, iya kan ti o fi tọkantọkan sin Ọlọrun, orilẹ-ede Israẹli jẹ anfaani ọgbọn ati itọsọna Ọlọrun nipasẹ ọ̀kan ninu awọn wolii ti o ga ju lọ. O kọ́ ọmọ rẹ̀ ni igbọran ninu ile, ati ibẹru Ọlọrun, eyi ti o pese ọkàn rẹ̀ silẹ lati dahun bayii nigba ti Ọlọrun pe e: “Ma wi; nitori ti iranṣẹ rẹ ngbọ́.”

Ro o wò, ki ni i ba ti ri fun Israẹli bi o ba ṣe pe kò si ẹni kan ti o ti ṣe ifararubọ “lati gba oguṣọ naa” nigba ti ina Ọlọrun fẹrẹ kú tán lọwọ Eli. Ọlọrun ki i ṣe alairi ẹni kan ti O le gbẹkẹle, ẹni ti yoo “di odi mu” nigba ti o dabi ẹni pe isin Kristi n ku lọ. Ta ni ẹni naa ti o n ṣe ifararubọ lonii ti Ọlọrun yoo le gbẹkẹle, ti o n pese ara rẹ̀ silẹ fun ọjọ ọla, ki o ba le wi pe, “Emi nĩ; rán mi”? “Ki iṣe ti arojuṣe bi awọn ti nwù enia; ṣugbọn gẹgẹ bi awọn ẹrú Kristi, ẹ mã ṣe ifẹ Ọlọrun lati inu wá” (Efesu 6:6).

**A n Fẹ́ Awọn Iya Ẹni iwa-bi-Ọlọrun Lonii**

Ayé isisiyii n fẹ́ awọn iya ẹni iwa-bi-Ọlọrun; awọn Hanna igba isisiyii fun akoko ewu ti a wà yii. Aibọwọ fun aṣẹ awọn obi ti o si n ṣe okunfa ainaani ofin Ọlọrun ati ti eniyan ni o mu ki orilẹ-ede kun fun awọn jagidi-jagan ọmọ, ti apa awọn alabojuto ofin to jafafa ju lọ ni ilẹ wa ko ka mọ́. Ọna kan ṣoṣo ti a le gba yọ ninu iṣoro buburu yii ni ki a sọ ile wa di ile ẹni iwa-bi-Ọlọrun ninu eyi ti a o maa kọ́ awọn ọmọ ni ọna ti wọn o rìn.

Wo o bi o ti jẹ iriri ti o tu ni lara tó lati ri igbesi-aye obinrin ti o fẹran Ọlọrun ti o si ka a si ohun pataki lati fi otitọ Ọrọ Ọlọrun kọ́ awọn ọmọ rẹ̀! Alaafia ati ibukun Ọrun yoo wà lori iya naa ati ẹbi ti o tẹle ipa ọna yii. Ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn iya ni o maa n mu ki o ni iwuwo lọkan fun ọna awọn ara ile rẹ (Owe 31:27), ti yoo si fi tọkantọkan boju to itọni awọn ọmọ rẹ̀, ki wọn ba le di ọlọgbọn si igbala (2 Timoteu 3:15), ki wọn má si dẹ́ṣẹ si Ọlọrun (Orin Dafidi 119:11).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ohun pataki ti a ri ninu ile Hanna?
2. Ki ni a n beere lọwọ Hanna ki o ba le ri ibeere ọkàn rẹ̀ gbà?
3. Ki ni ohun ti a ni lati ṣe ki a ba le ri idahun si adura wa?
4. Njẹ Hanna ka ẹ̀jẹ́ rẹ fun Ọlọrun si ohun pataki?
5. Njẹ o pẹ́ ki o to san ẹ̀jẹ́ rẹ̀?
6. Ki ni mu ki awọn ọdọ kun fun iwakiwa gbogbo?
7. Bawo ni Bibeli ti ni ki awọn obi maa tọ́ awọn ọmọ wọn?